ati paapaa fun àlejò. (Rom 12:13;
Heb 13:2.)
6. Ti wọn njẹ̀rìí si ìfẹ rẹ niwaju ìjọ: ìwọ
yoo si ṣe rere bi iwọ bá sin wọn siwaju
lọ̀na ìrin-àjò wọn gẹgẹ bi o ti yẹ ninu
Ọlọrun. (A.A. 15:3; Tit 3:13.)
7. Nitori pe nitori orukọ rẹ̀ ni wọn
ṣe jade lọ, laigba ohunkohun lọwọ
awọn Keferi. (A.A. 5:41; 20:33,35.)
8. Nitori naa o yẹ ki a gba irú awọn
wọnyìí, ki awa lè jẹ́ alabaṣiṣẹ pọ̀ pẹlu
otitọ.

**Ìbáwí fun Diotrefe.**

9. Emi kọwe si ijọ: ṣugbọn Diorefe,
ẹni ti o fẹ́ lati jẹ olori laarin wọn, kò
gbà wá. (2 Jhn 9.)
10. Nitori naa bi mo bá dé, emi o
mu iṣẹ rẹ̀ ti o ṣe wá si iranti, ti o nsọ
ọ̀rọ buburu ati isọkusọ sí wa: eyiyìí ko
si tẹ ẹ lọrun, sibẹ oun tikararẹ kọ̀ lati
gbà awọn ará, awọn ti o si nfẹ gbà
wọn, o ndá wọn lẹ́kun, o si nle wọn
kuro ninu ijọ. (2 Jhn 12; ẹsẹ 5; Jhn
9:34.)

**Ìyìn fun Demetriu.**

11. Olufẹ máṣe ṣe afarawe ohun ti i
ṣe ibi, bikoṣe ohun ti i ṣe rere. Ẹni ti ó
bá nṣe rere ti Ọlọrun ni: ẹni ti o ba nṣe
buburu ko ri Ọlọrun. (Psm 37:27; 1
Jhn 2:29; 3:6,9.)
12. Demetriu ní ẹrí rere lọdọ
gbogbo eniyan ati ní ti otitọ tikararẹ
pẹlu: nitootọ, awa pẹlu si gba ẹ̀rí rẹ̀ jẹ́;
ẹyin si mọ pe ẹrí wa otitọ ni. (1 Tim
3:7; Jhn 21:24.)

**Ọ̀rọ̀ Àsọ́parí.**

13. Emi ní ohun pupọ lati kọ̀wé si ọ,
ṣugbọn emi kò fẹ́ fi jẹlú-ìkọ̀wé ati gè-
gé kọ wọ́n. (2 Jhn 12.)
14. Ṣugbọn mo ni ìrètí lati ri ọ láìpé,
a o si sọ̀rọ̀ lójúkojú.
15. Alaafia fun ọ, Awọn ọ̀rẹ́ ki ọ! Ki
awọn ọ̀rẹ́ ni orukọ-orukọ! (1 Pet
5:14.)

65

# JUDA

**(A.D. 66)**

## ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ iṣaaju.**

JÚDA, iransẹ Jesu Kristi, ati ara-
kunrin Jemisi , si awọn ti a pè, olufẹ
ninu Ọlọrun Baba, ti a si pamọ fun
Jesu Kristi: (A.A. 1:13; 1 Pet 1:5.)
2. Ki aanu, ati alaafia, ati ìfẹ́ maa bí
si i fun yin. (1 Pet 1:2; 2 Pet 1:2.)
3. Olufẹ, bí mo ti nlàkàkà pupọ lati
kọ̀wé si yin niti ìgbàlà ti i ṣe ti gbogbo
eniyan, nkò gbọ́dọ̀ ṣàìmá kọ̀wé si yin,
ki nsì gbà yin niyanju lati maa jà gidi-
gidi fun igbagbọ, ti a ti fi lé awọn
eniyan-mimọ lọ́wọ́ lẹẹkanṣoṣo. (Tit
1:4; 1 Tim 6:12.)
4. Nitori awọn eniyan kan nbẹ ti
wọn nyọ́ wọle, awọn ẹni ti a ti yàn lati
igba àtijọ́ si ẹ̀bi yìí, awọn alaiwa-bi-
Ọlọrun, ti nyi oore-ọfẹ Ọlọrun wa
padà si wọbia, ti wọn si nsẹ́ Oluwa
kanṣoṣo naa, ani Jesu Kristi Oluwa
wa. (Gal 2:4; 2 Pet 2:1; Rom 9:22.)

**Ìwà ati iparun awọn olukọ èké.**

5. Njẹ emi nfẹ lati rán yin leti bi ẹyin
tilẹ̀ ti mọ̀ gbogbo rẹ̀ lẹẹkan ri, pe Olu-
wa, nigba ti o ti gba awọn eniyan kan
là lati ilẹ Egipti wá, lẹhin naa o run
awọn ti kò gbagbọ. (Num 14:29; Psm
106:26.)
6. Ati awọn angẹli ti kò tọ́jú ipò ọlá
wọn, ṣugbọn ti wọn fi ipò wọn silẹ̀,
awọn ni o ti fi pamọ ninu ẹ̀wọ̀n aini-
pẹkun nisalẹ̀ okunkùn de idajọ ọjọ
nla. (Jhn 8:44; 2 Pet 2:4; Ifh 20:10.)
7. Ani bi Sodomu ati Gomora, ati
awọn ilu àgbègbè wọn, ti fi ara wọn
fun àgbèrè ṣíṣe bakan naa, ti wọn si
ntẹ̀lé ara àjèjì lẹhin, awọn ni a fi lelẹ

bi apẹẹrẹ, wọn njiya iná ainipẹkun. (2 Pet 2:6; Gen 19:24.)

8. Bakan naa ni awọn wọnyìí pẹlu nsọ ara di eeri ninu àlá wọn, wọn si ngan àṣẹ, wọ́n sì nsọ̀rọ̀ eebú sí awọn ẹni-ògo. (2 Pet 2:10.)

9. Ṣugbọn Mikaeli, olori awọn angẹli, nigba ti o nba Èṣù jà, ti o nṣe àríyànjiyàn nitori òkú Mose, kò sì gbọdọ sọ ọ̀rọ̀-òdì si i, ṣugbọn o wi pe, "Oluwa ni yoo ba ọ wi!" (Dan 10:13; Sek 3:2.)

10. Ṣugbọn awọn wọnyìí nsọrọ-odi si ohun gbogbo ti wọn kò mọ̀: ṣugbọn eyi ti wọ́n sì mọ̀, pàápàá nipa àdánidá, bi ẹranko aláìlọ́gbọ́n inú, ninú awọn nkan wọ̀nyí naa ni a npa wọ́n run. (2 Pet 2:12; Filp 3:19.)

11. Egbé ni fun wọn; nitori ti wọn ti rìn ni ọna Kaini, wọn si fi iwọra sure sinu ìṣìnà Balaamu nitori èrè, wọn si ṣègbé ninu iṣọtẹ Kora. (Gen 4:3–8; 1 Jhn 3:12; Num 22:7; 2 Pet 2:15; Num 16:1–3; 31–35.)

12. Awọn wọnyìí ni o jẹ abàwọ́n ninu àsè ìfẹ́ yin, nigba ti wọn nba yin jẹ àsè, awọn oluṣọ-agutan ti nbọ́ ara wọn laibẹ̀rù: ikuukuu laini omi, ti a nti ọwọ afẹ́fẹ́ gbá kiri; awọn igi alaileso ní àkókò èsó, wọn kú lẹẹmeji, a fa wọn tu ti gbòngbò ti gbòngbò (2 Pet 2:13; 1 Kor 11:20; Ef 4:14; Matt 15:13.)

13. Omi okun ti nrú, ti nho ìfòòfó ìtìjú ara wọn jade; alarinkiri ìràwọ̀, awọn ti a pa òkùnkùn biribiri mọ́ dè laelae. (Isa 57:20; Filp 3:19; 2 Pet 2:17.)

14. Awọn wọnyìí pẹlu ni Enoku, ẹni keje lati ọdọ Adamu, sọtẹ́lẹ̀ fun, wi pe, "Kiyesi i, Oluwa mbọ pẹlu ẹgbẹgbaarun awọn eniyan rẹ̀ mímọ́, (Gen 5:18; Deut 33:2; Dan 7:10.)

15. Lati ṣe idajọ gbogbo eniyan, lati dá gbogbo awọn alaiwabi-Ọlọrun lẹbi niti gbogbo iṣẹ aiwabi-Ọlọrun wọn, ti wọn ti fi aiwabi-Ọlọrun ṣe, ati niti gbogbo ọ̀rọ̀ lile ti awọn ẹlẹ́ṣẹ̀ alaiwabi-Ọlọrun ti sọ si i." (2 Pet 2:6; 1 Tim 1:9.)

16. Awọn wọnyìí ni awọn ti nkùn, awọn aláròyé, ti nrin nipa ifẹkufẹ ara wọn; ẹnu wọn a maa sọ ọ̀rọ̀ ìhalẹ̀, wọn a maa sojúsaju nitori èrè. (2 Pet 2:18.)

**Ìkìlọ̀ lati di Igbagbọ otitọ mú.**

17. Ṣugbọn ẹyin olufẹ, ẹ ranti awọn ọ̀rọ̀ ti a ti sọ ṣaaju lati ọwọ́ awọn Aposteli Oluwa wa Jesu Kristi. (2 Pet 3:2.)

18. Bi awọn ti wi fun yin pe, "Awọn ẹlẹ́gàn yoo wà nigba ikẹhin, ti wọn o maa rin gẹgẹ bi ifẹkufẹ aiwa-bi-Ọlọrun ti ara wọn." (1 Tim 4:1; 2 Pet 2:1.)

19. Awọn wọnyìí ni awọn ẹni ti nya ara wọn si ọ̀tọ̀, awọn ẹni ti ara, ti wọn kò ní Ẹmí. (1 Kor 2:14,15; Jak 3:15.)

20. Ṣugbọn ẹyin, olufẹ, ti ẹ ngbe ara yin ró lori igbagbọ yin ti o mọ́ julọ, ti ẹ ngbadura ninu Ẹmí Mímọ́ (Kol 2:7; Ef 6:18.)

21. Ẹ maa pa ara yin mọ́ ninu ifẹ Ọlọrun, ẹ maa retí aanu Oluwa wa Jesu Kristi titi di ìyè ainipẹkun. (Tit 2:13; 2 Pet 3:12.)

22. *Ẹ maa yí wọn lọ́kàn pada, ani awọn ti nṣiyemeji; (Tit 1:9.)

23. Ki ẹ sì maa gba awọn ẹlomiran là, nipa fi fà wọ́n yọ kuro ninu iná: ki ẹ si maa ṣaanú pẹlu ìbẹ̀rù, ki ẹ si korira ẹ̀wù ti ara ti sọ di eeri. (Sek 3:2–5; 2 Kor 5:11.)

**Oore-Ọ̀fẹ́.**

24. Njẹ ti ẹni ti o le pa yin mọ́ kuro ninu ìkọsẹ̀, ti o si lè mu yin wá siwaju ogo rẹ̀ láìlábùkù pẹlu ayọ̀ nla, (Rom 16:25; Ef 3:20; Kol 1:22.)

25. Ti Ọlọrun ọlọ́gbọ́n nìkanṣoṣo, Olugbala wa, ati ọlá ńlá, ijọba ati agbara, ni isinsinyìí ati laelae. Amin. (1 Tim 1:17; Rom 11:36.)

---

(22, 23) *(Ede Griki ti a fi kọ gbólóhun-ọ̀rọ̀ ti nbẹ ninu ẹsẹ bibeli meji yìí, doju rú pupọ. Ṣugbọn nipasẹ Ẹmi Mimọ a ri itumọ ti o yẹ fun un (ju bi awọn bibeli atijọ miran ṣe tumọ rẹ). Awọn ẹsẹ bibeli atọ́ka ti nbẹ lábẹ́ ẹsẹ meji naa pàápàá sì ba itumọ naa mu: Lẹnu ẹlẹri meji yii, Ẹmi-Mimọ ati Ọrọ naa, a fi idi otitọ ọrọ naa mulẹ̀.)